GO PLACES IN A HILLMAN FROM ARAB BROS MOTORS LTD.

# IROHIN IMOLE

MOTTO: IMOLE DE, OKUNKUN PARADA.

**Akiyesi Pataki**

A fi eyi şe ikede fun gbogbo awọn Ọmọ Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye wipe ẹn kẹni ti o ba fi ibiti a sọ pe ki wọn ge silẹ ti ko ge ti ko si fi stampu Tọrọ sinu rẹ ki Olawa rẹ maşe ni ero pe on y'o jẹ ọkan ninu awọn ọmọ ẹgbẹ na, a ko si ni da esi pada si i.

Ki alafia ma ba nyin gbe.

AKOWEAGBA

VOL. V No. 203 MONDAY JULY 10 — JULY 16 1961 KỌBỌ KAN (1d)

# Gomina apapo Ile Naijiria ti fi Ase si, nipa iwadi Ile'fowo pamosi ti National Bank

EKO:- Ejọ ti a gbọ Dingle Foot Fi şe atẹgun ọrọ rẹ ni wipe Ololu Ijọba ko laşẹ lati yọju sinu ọrọ ile Ifowo pamọsi kan, aya fi ki aşẹ na wa lati ọdọ Gomina agba. Şamọşamọ ọrọ na ko jẹ bẹ, Ọ'ola Abu sọ wipe, on ti gba aşẹ lati ọdọ Gomina agba, ki on to paşẹ pe ki nwọn lọ şe iwadi ọrọ ile owo na (Bank) Ọgbẹni W. A Wheeler ti o jẹ alatako si ile owo na, fi iwe han Adajọ ni biti Prime Minister ati Gomina agba gbe ba ara nwọn sọ ọrọ ao şe iwadi tabi a ko şe iwadi ile owo yi, on na lo si fun Ọlọla Vahe ni aşẹ lati şe iwadi rẹ. Ibẹ ni ariyanjiyan ba bẹrẹ larin Dingle Foot Agbẹjọro fun Bayọ Doherty Ọgbẹni Wheeler Agbẹjọro fun Ijọba.

Iwadi ti Ijọba Alapapọse Naijiria so wipe ki a se nipa ise si ati ilọsi National Bank of Naijiria ti nwọn si ti mura lati şe iwadi na ki Ọgbẹni Bayọ Doherty to wa dahun wipe, Ijọba ko ni ẹtọ lati sọ wipe, ki awọn enia kan wa tun penpọọ şewadi nipa işesi ati ilọsi Bank na.

Lowurọ ọjọ Eti ti o kọja lọ ni agogo mokanla.

Ni nwọn iba bẹrẹ iwadi na, ki Adajọ Agba, Alexander Bellamy ti işe igbakeji Adajọ agba Kotu Garran, to wa fi oke le ọrọ na wipe, on gba wipe, ki a si da ọrọ iwadi na duro na, titi awọn yio fi yanju ọrọ nla rabata kan ti Ọgbẹni Bayọ Doherty gbe kalẹ lati ọwọ Ọgbẹni Dangle Foot Q.C.

Ọgbẹni Dingle Foot fẹ ki on ba Ijọba Alapapọse jagun ki on si tọka si ofin kan ti ko fun Ijọba na ni aşẹ lati şe iwadi nipa Bank na Nigbana ti Adajọ Alexander ba paşẹ pe Ọlọla Vahe ti ise oluwadi ọrọ na pe, ki o simẹdọ na, titi ki a fi gbọ iru ofin na ti Dingle Foot yio mu wa.



Oloye T. A. BAYO DOHERTY

Dingle foot bere pe, iwe ofin wo lo sọ bẹ? Ọgbẹni Wheeler si dahun pe, S. A. De Smith lo şe iwe ofin na, o tun bere pe, kini oye rẹ ninu ẹkọ, o dahun pe Ph. D. (Law) Foot si wipe ko ha tan na, Whee'er si dahun pe eyiti adajọ ba sọ ni mo fi ara mọ. Ẹjọ na yio bẹrẹ loni.

## Ero Oloye Awolowo fun gbogbo Ile Enia Dudu

Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ, baba ẹgbẹ Afẹnifẹre, jakejado gbogbo Naijiria nfẹ ẹgbẹ nla kan ti yio şişẹ tọkantọkan fun ominira kikun enia dudu. Oloye tọka si pe ilẹ Afrika ko kuro ninu igbekun rara. Awọn ilu ti o dabi ẹnipe nwọn ni ominira ko kuro ninu ẹwọn oyinbo; alawọ funfun ni o si npaşẹ fun wọn labẹlẹ. Ni ilu bi Kẹnya, ati Algeria, bi o ti lẹ jẹpe alawọ dudu ni o pọju, ti alawọ funfun si kere doye ni' alawọ funfun ni o njọba lori wọn. O tilẹ buruju ni ilẹ Afrika ti iha Gusu nibiti nwọn ti nşe ọmọ enia dudu bi ẹran, Ọlọla Obafẹmi ran wa leti pe iku Lumumba, olori kongo ko hin awọn oyinbo, nitoripe nwọn ko fẹ lọ ni dọ ọlọra, ilẹ afrika. Ilẹ Angola njiya lọwọ lati ọwọ oyinbo Pọtogi nitoripe awọn ara ilu Angola nfẹ ominira Ko si si ẹsẹ miran ti nwọn şe npa wọn

Oloye Awolọwọ ni nitori irufẹ nkan wọnyi ati ọpọlọpọ ti ko le ri aye lati sọ inu ọrọ rẹ, ni on şe nfẹ ẹgbẹ kan ti yi o wa fun Igba-ara-ẹni-silẹ lọwọ igbẹkun alawọ funfun. Oloye ni gbogbo ọmọ Afrika ni lati so ọwọ pọ nitori ajeji ọwọ kan ko gbe ẹru dori, ori yio si jẹ anfa ni nlanla fun Afrika bi ilẹ Afrika ba le so ọwọ pọ lati şişẹ ilọsiwaju pẹlu awọn ilẹ miran ti o ni ifẹ wa nitotọ.

O ni aisaşọ lọrun paka, o to apero gbogbo mariwo, nitorina işẹ gbogbo ọmọ Afirika ni lati sowọ pọ ati lati mu ilẹ wa kuro ninu ẹwọn alawọ funfun.

Ki eyi ba le şe şe, oloye fẹ ki a ni ẹgbẹ nla kan fun gbogbo ilẹ Afirika. Ẹgbẹ yi yio ma gba ẹgbẹ Oşelu lati ilu ki ilu ni Afrika sinu ẹgbẹ, şugbọn ki yio gba Ijọba ilu kankan.

Idi eyi ni pe, ti Ijọba ba wa hinu rẹ, işoro pupọ yio wa la ti şe ohun ti a fẹ şe ni ọna kini pupọ ninu ijọba ni alawọ fun fun npaşẹ ni abẹlẹ, iru Ijọba ba yi ko si ni le şişẹ tọkan tọkan ki a le bo ajaga oyinbo patapata. Ni ọna keji irufẹ ijọba ilẹ Afrika ti iha Gusu ki yio di ọmọ ẹgbẹ nitori iwa buruku wọnsi alawọ dudu. Şugbọn ti o ba jẹ pe ẹgbẹ oşelu ta pe ẹgbẹ ti o wa fun ominira enia dudu nikan yio wa ni ẹgbẹ, iru ẹgbẹ bayi ti o wa ni ilẹ Afrika yio ni anfani lati so ọwọ pọ ati lati şişẹ fun ominira Afrika pẹlu enia dudu yoku. Oloye ni yio jẹ ọkan ninu ofin ẹgbẹ yi nigbati a ba da silẹ pe ẹgbẹ kẹgbẹ ni ilu ki lu ti o ba nran awọn oyinbo lọwọ lati m , fi wa si igbẹkun yio kuro ninu ẹgbẹ, awọn ẹgbẹ ti o ku ki yio si ba şe ohunkohun mọ.

AWỌN IWE KO ṢE MANI

IWE EGBOGI FUN ONIRURU IWOSAN; IWE ADURA IṢẸGUN AWỌN AJẸ; IWE IFA AGBỌN-NIREGUN, IWE ITUMỌ ALA PẸLU IWADI NKAN; IWE LILO ATI AGBARA PSALMU:

★ ★ ★ ★ ★ ★

IWE ADURA TETE DA MI LOHUN;

IWE ITAN ABALAIYE ATI TI IṢẸDALE.



KỌWE FUN IWE-ITAJA:-

OLOTU BOX 104
EBUTE METTA, NIGERIA.

**For all your Printing Requirements**

Invitations, Programmes, Hand Bills, Pamphlets, Advertising Material and all Commercial Jobbing

Send your Jobs to :-
MODUPE PRINTING PRESS.
16, Bamgbose Street, Lagos. Phone: 21985

Where Quality Print, costs less.

## Electricity Corporation of Nigeria

### OHUN TI O FA SABABI TI INA KO FI TAN NILU LAIPẸ YI

Awọn oji tabi ẹfufu Jile ti oja kọja lọ laipe yi, ba ogunlogọ opo ina lẹntiriki ti o ṣubu lulẹ ti waya sija gbogbo jamba ti ẹfufu na ṣe jẹ, ọgota-le-lọdu run. Mejile-ladọta lo leju ninu awọn jamba na, oja waya ti ata si oke, o si ba eyi ti o wa ni abẹlẹ jẹ. Ni eyiti ojẹ wipe, igba ile lo ngba ilẹ tanna sinu ile wọn. Awọn ina ti o tun bajẹ ni eyiti a so pọ mọ waya ni opopo ode lati ma fi tan ina ile. Gbogbo jamba na' nla ati kekere ni awọn oniṣẹ ẹrọ lẹntiriki ti fẹrẹ yanju tan, awọn oṣiṣẹ onina na ko simi lọsan ati loru kuro ninu iṣẹ atunṣe na. A si rope laipẹ, nwọn o pari gbogbo iṣẹ na, ina yio si ma tan niṣo laisi idaduro. Awọn olotu ile iṣẹ ina lẹntiriki kẹdun jọjọ fun alaikori ina tan lẹnu ọjọ yi, ati wipe atunṣe na ka wọn laiya ni ko ṣe jẹki a ri ina tan. Bi o ti wu ki o ri, a o ma gbiyanju lati tunbọ tẹra mọ iṣẹ na ni gbogbo igba.

G. E. Wyatt. Chief Executive Officer
Ati General Manager.

## IROHIN IMOLE DARABA

## Mo ngbadun Oro Ogbeni Ajegboro Dagba

L ti Ọwọ:- ORIRE'TEMI T. ADEYANJU (AGEGE)

Mo dupẹ lọwọ o'otu ti ofun mi laye dẹ lati gbe Ajẹgborodagba lesẹ. Mo ki gbogbo yin Ẹnyin Onkawe Irohin Imọlẹ, Mo tun ki Ọgbẹni wa Ajẹgborodagba ati Olotu, Irohin Imọlẹ. Mo si tun ki awọn Onitẹwe ati awọn to tun ta we pẹlu awọn to tun rawe Irohin Imọlẹ. Ẹ ku əs Ọlọrun ko ran wa lọwọ o Amin.

Ninu Iwe Irohin Imọlẹ ti Ọjọ Monday ti se 26:6:61, ni Ọgbẹni Ajẹgborodagba fi han pe Iwa ti wọn nhu ni Naijiria ko dara, Emi na fi ara mọ bẹ. Sugbọn gbogbo, wa ni Naijiria korira iwa buruku yi. Awọn Agba ti npa li owe pe "ẸNI BURUKU BA ẸNI RERE JẸ,, ohun ti ojẹ ki won pe Naijiria fun gbogbo apapọ rẹ ni yẹn.

EMI ỌMỌ ADE, fẹ fi han yin ohun ti ojẹ ki iwa yi pọ leko (1) Eko jẹ Ilu ti ogba Ole ti o si gba Olẹ. (2) Awọn Ọmọ ako fi Emi di Iku ọmọ ati alaimo Ẹwọn ni nkan kan gbọni Itẹ Iku Igbọro ni ọna Ajẹ, pẹlu pe ko si ọlọpa ti o le gbaiya ki o lọ mu wọn ni bẹ, afi Eyiti oba ro ọka tan ni aiye ti ofẹ lọ fi ọbẹ jẹ lọrun. Diẹ ni awọn Ọlọpa le ṣe nibẹ Eyiti oju nipe ki wọn da ọwọ igbo na duro bi oba jẹ wipe wọn nse Igbo na ni. Bi wọn ko ba ri ra mọ, Wọn ko ni mọ, ki awọn Ọlọpa ti ki wọ Asọ se Iṣẹ yi bi Iṣẹ, Awọn C. I. D. ni mo wi o

Ẹniti wọn ba ri mu pẹlu iwa buruku yi ki Ijọba fani rẹ bi ofin rẹ ti yẹ Ninu awọn Ọmọ Onimọto Bọlẹkaja ni iwa buruku yi pọ si lọdọ. Nipa ṣṣe eyi wọn yio di iya iwa buruku yi ku, Nipa ti tẹtẹ ti Ọgbẹni wa Ajẹgborodagba sọ, diẹ niyẹn lẹgbẹ Igbo mimu, onitara ni yio mọ itara ara rẹ, bi o ba dija lara wọn ni Ọlọpa le to mu wọn, Nitorina bi wọn ba ni ki Ọlọpa ma mu wọn tori ọrọ yi, ọpọlọpọ ni wọ yio ma mu ti ki ṣe tẹtẹ nwọn nta, nitoripe Oyinbo ti o ṣe Ludo ati Dirafiti ko ṣe fun tita tẹtẹ. Awọn ẹlomiran ko si ra fun tita tẹtẹ ṣugbọn fun Idaraya ọwọ ni wọn nta ti wọn nta.

## KERE O! Akiyesi Pataki

### Antoin Tablets! Antoin Tablets!!

Ẹnyin Abiyamọ lọkunrin ati lobirin. Mo ba yin yọ Ẹku afojuba Egbogi pataki ti aṣe iwadi rẹ lati ọwọ awọn Ọjọgbọn Onişegun (Specialists) Ilu Oyinbo.

Fun awọn ajakalẹ Arun wọnyi:-

IGBONA:- Eyi jẹ Arun ti o sọpọ ni ode isisiyi papa ni arin awọn Ọmọde ati Agbalagba.

ORI FIFỌ. TULU. LUKULUKU. OTUTU. IGBAAYA ARA RIRO ati OTUTU ỌRẸRẸN pẹlu AKOKORO. Jọwọ danwo Ajẹhidan ni ogun yi. Irohin ko to Afojuba

Bere iwe ti ẹ o fi lo lọwọ ẹniti o ba ta Egbogi na fun yin. Odaju hanwun. Iṣ o ri iṣẹ rẹ lẹhin iṣẹju mẹdogun ti ẹ lo. Bere lọwọ awọn Onişegun adugbo rẹ.

*Distributors*

HASSAN COMMERCIAL MEDICINE STORES
26, Bishop Street Phone: 23745
LAGOS

### ỌGBẸNI D. H. L. PARKER TI IṢE PUBLIC RELATIONS MANAGER FUN AWỌN OYINBO ONIṢOWO U. A. C. NI EKO LO FUN ISIMI OṢU MEJI NI ILU OYINBO

Ni ọjọ Iṣẹgun ti ṣe ọjọ kẹtadinlọgbọn oṣu yi ni irohin tẹwa lọwọ pe Ọgbẹni D H. L. Parker ti ṣe Ọga agba ati alabojuto ibi iṣẹ U. A. C ti anpe ni Public Relations fi Eko silẹ lọ fun isimi Osu meji. Awọn ibiti yio si lo isimi na ni Erekusu kan ti a npe ni Canary Islands ati ni ilu Oyinbo Ni asiko isimi Ọgbẹni Parker yi Ọgbẹni O. O. Asuquo ti ise Olotu Iwe Irohin ti a npe ni U. A. C. News ni yio de le de e. Ọgbẹni Asuquo ti o ti wa ni ibi iṣẹ U. A.C. kan ni Ilu Oyinbo lati bi osu mẹta sẹhin yio bẹrẹ si iṣẹ adele rẹ bi o ba ti pada de ninu oṣu ti nbọ yi. Fun asiko diẹ ti o ku ki Ọgbẹni Asuquo pada si Eko Ọgbẹ Ifaturoti ti o jẹ igbakeji fun Ọgbẹni Parker ni yio wa ni ipo Adele.

